# ELETI ỌFẸ

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 832 LAGOS SATURDAY AUGUST 11, — AUGUST 17, 1962. KOBỌMEJI (2D)


AWON IBEJI TI KO NI ABAWAIYE :

# Iya To Bi Abami Omo Ku Awon Omo Paapa Tele

SAPẸLẸ— Gbogbo awọn oṣiṣẹ ile alaisan ilu Sapẹlẹ ni nwọn nsare sihin, sare sọhun lati gba obinrin aboyun kan ti o nrọbi la ni ijẹta Ọjọbọ tiṣe ọjọ kẹsan osu yi. Obinrin aboyun na bi; ṣugbọn abami ibeji alalẹpọ ni awọn ọmọ ti o bi.

Nwọn ko mọ orukọ obinrin na, irohin ti a gbọ lati ọdọ onirohin wa ni wipe obinrin yi ti wa lori ikuunlẹ ti o nrọbi tipẹ ki awọn ẹbi rẹ to gbe wa si ile alaisan yi.

Gbara ti Dokita O. Norman Williams, ọga ile awọn alaisan na, ti foju kan aboyun na ti o yẹ ẹ wo, o ni a fi ti awọn ba yọ ọmọ inu rẹ na jade. Nigbati nwọn si ṣe iṣẹ fun obinrin na, awọn ibeji alalẹpọ ni nwọn ba ninu rẹ.

Awọn ọmọ na lẹmọ ara wọn laya, nwọn ni ori meji, ọwọ mẹrin ati ẹsẹ mẹrin, sugbọn nwọn ko ni abawaiye, ko si ẹniti o le sọ bi obinrin ni wọn tabi ọkunrin. Okumọ ni o bi wọn, iya paapa si ku pẹlu.

Nwọn ti ko awọn oku ọmọ na sinu igo ninu ile iṣẹ awọn dokita fun lilo awọn dokita ti nkọ iṣẹ bi nwọn ti nlo abẹ.

---

Ile Ise Siga Nlo Si Ilorin

## Oba Sulu Gbayi Lowo Alufa Padi

ILỌRIN — Lẹhinti Ọlọla Ahmadu Bello, Sardauna Sokoto, ti da Ọba Ilọrin, Mallam Sulu Gambari lọla pẹlu ida aṣẹ nṣe ni ọla tun yi lu ọla si fun Ọba na. Onirohin Eleti-Ọfẹ tẹ waya si wa wipe Alufa agba ijọ awọn ẹlẹsin Aguda ti nwọn npe ni Pope John fi mẹdali oni silifa kan ranṣẹ si Ọba na pẹlu ọrọ atata wipe on kan saara si Ọba na fun bi o ti nṣe si awọn ọmọ ijọ Ṣọsi on ti nwọn wa kakiri gbogbo ilẹ awọn Igbimọna kakiri agbegbe Ilọrin.

Oguna gbongbo Alufa Padi ti o wa jẹ iṣẹ na lati Rome ni Eniọwọ Cardinal Montini John (the Baptist) Bisọbu agba ni Ṣọsi Aguda ni ilu Milan ni Itali; Padi yi si mu Monsignor Pigne Doli, Alufa Padi agba ni Iwọ Orun Afrika lọwọ lọjọ ti o nlọ jiṣẹ yi fun Ọba Ilọrin ni Agbala Ọba na.

Ọba Ilọrin paapa dupẹ lọwọ Pope ninu aṣeyẹ ti ṣe fun awọn alejo na, o ni ki nwọn ba on kii pupọ.

### Ile Ise Siga

Awọn Oyinbo onisowo aladapọ kan ti fi owo tabua (£500,000) silẹ fun iṣẹ siga ti nwọn fẹ da silẹ ni ilu Ilọrin. Nwọn ni Kwora Tobacco Company ni awọn a ma pe ile iṣẹ na. Eleyi a jẹ ki awọn ọmọ Ilọrin ri iṣẹ ṣe. Igba (200) enia ni nwọn yio gba si ibi iṣẹ na ti nwọn ba kọ ọ tan.

---

### Oba Adele Yo Awon Oloye Re

Ẹ GBỌ ELEYI! ADELE YỌ AWỌN OLOYE MARUN LOYE —— Awọn oloye na ni Oloye Kosọkọ, Ọbanikoro, Olorogun, Onilẹgbalẹ, ati Olumẹgbọn. Nwọn ri iwe gba lati ọwọ Ijọba ni oru alẹ ana wipe awọn ko gba wọn ni oloye mọ. — Ayiluka —

---


**LAGOS RACE CLUB**

Third Day

August Race Meeting

TODAY

First Race 3. 15 p. m.

**Come One Come All.**

Hon. Secretary,
Lagos Race Club.

# Awo Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Ma fi akoko jafara. Irohin daradara kan n kan ẹ lọwọ nipa iṣẹ rẹ.

PISCES (Feb 21-Mar 20) Ọsẹ yi dara pupọ fun ọ ṣugbọn ki o mọ ba wọn kẹgan ẹnikan rara.

ARIES (Mar 21-April 20) Ṣọra pupọ ki o si mase lọwọ nka ti o le fa dasu-Capọ ba ẹ. Boya o le gburo rere kan nipa awọn ominowo lati ilu okere.

TAURUS (April 21-May 20) Ki o ṣe pẹlẹpẹlẹ, ki o si mọ bi wa ti ma ba awọn ti o jẹ ẹ lọ sọrọ lọsẹ yi. Ki o ko ara rẹ ni ijanu daradara.

GEMINI (May 21-June 21) Ti o ko ba ti gbeyawo ri, ọrọ nkan ti o jẹmọ ọrọ a lẹ gbe iyawọ a yọ si ọ. Ti o ko ba si mura daradara wa ri idiwọ amubọ diẹ.

CANCER (Jun 22-July 23) Wa nkan miran ki o ṣe bi o ba ri wipe nkan ko lọ dede si bi o ti roo si. Maṣe ba wọn gbe iyawo pajawiri rara ninu ọsẹ yi, ewu wa nibẹ.

LEO (July 24-Aug 22) Ti o ba jẹ ọdọ ki o lọra lati ba wọn lọ si irin ajo ti airotẹlẹ Owo a yọ si ẹ lọwọ lojiji ninu ọsẹ yi tabi ki o jẹ ogun enia kan.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ijọra kan wa niwoju rẹ, o ni lati mu suru pupọ pẹlu ọgbọn lati fi yanju iṣoro na.

LIBRA (Sep 24-Oct 23) Irohin rere pelu ipinav daradara ni tirẹ, sugbọn ki o tete mu ogiri si iṣoro ti o ba fẹ yọju si ọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ookudjo-ko-a-bo kan wa ninu ọrọ rẹ. Okan-eni ni olufa ẹni, nitorina ọna ti ọkan rẹ ba sọ ẹ si ni ki o gba.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Ki o fi ọgbọn inu dahun ibere kan ti awọn ẹnikan yio bere lọwọ rẹ.

CAPRISCORN (Dec 23-Jan 12) Wa ri awọn enia ti nwọn yio ba ọ da inugian rere. Irawọ rẹ fọ ohun rere. Gbogbo nkan ti o ba si ṣe ri jẹ rere lọdọ awọn enia.

# Muyibi Alapata Komojade

PORTO NOVO— Laipẹ yi ni Ọgbẹni Muyibi Alapata ti ṣe Seriki awọn alapata ti o ngbe adugbo Mọsalasi Jimọ ṣe ikomọ ọmọbinrin ti iyawo rẹ Sidikatu Abudu Agbọnyin bi fun un jade. Nwọn sọ ọmọ na ni Adijatu Kubura. Alufa ti o ṣe isin eto ikomọjade na ni Alhaji Raimi. Gbogbo ẹsẹ awọn ti orukọ ẹgbẹ wọn njẹ Mejọriti, ti Alhaji Abiọdun nṣe olori ẹgbẹ na ni nwọn pejẹ sibẹ, nwọn si da aṣọ ẹgbẹ-jọda.

Inawo ọjọ na kamọmọ. Kelani Onilu lati ilu Abẹokuta ni owa fi ilu rẹ ṣe ere fun wọn. Baba ọmọ tuntun na si fi nkan jijẹ ati nkan mimu tẹ awọn ti o wa sibẹ lọrun.

Awọn diẹ ti a le darukọ niyi ninu awọn ti o wa si ibi ikomọ na. Alufa Yaya, Alhaji Kasumu, Alhaji Shitu, Ọgbẹni L. M. Adeṣina ("Onifaaji") Alhaji Tiamiyu, Alhaji Raimi, Alhaji Lasisi, Ọgbẹni Buari Adegbindi, awọn iya'fin Mogbadelọ Da Silra, Amudatu Muyibi, Sidikatu Muyibi, Wosilatu Adedeji, Rafatu Muyibi, Latifatu Abiọdun ati Riyanatu Balogun.

Oluwa ki o da ọmọ na si o.

# Omo Titun Alejo Aiye



**Aworan yi ni ti omokuriu kan ti iyawo ibatan Oba ilu Oyinbo ti nwon npe ni Duke Kent bi fun un ni loloyi. Baba omo tuntun na ni o wa ni apa otun ti o nye 'omo na wo pelu iya re lodi keji aworan yi. A gbo wipe baba omo na ni yio se asoju Oba ilu Oyinbo ni Uganda nigbati nwon ba nse ajoyo ominira ilu na ninu osu October.**

ELETO-ỌFẸ......

"Fun irohin atata lati ibikibi, ẹ ma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ ni ọsọsẹ ki ẹ polowo ọja nyin si inu iwe na.

ELETI-ỌFẸ......

# Arun Yapayapa De!

(LATI ỌWỌ OLOFINTOTO)

Bi enia ba pẹ pupọ ninu aiye ti a wa y. oju Oluwa rẹ a ri irikuri. Lẹhin ogun ajakaiye, ni iwọn nkan bi ọdun mẹrinlelogoji, ajakale arun kan ba gbogbo araiye ja ti gbogbo wa fun ni orukọ bayi "LUKU-LUKU" ṣugbọn suna ti awọn Oyinbo fun arun na ni Influenza. Arun yi tọmọde tagba ni o ba ja, ọkẹ aimoye enia ni o si pa bamu bamu lẹhin ogun ajakaiye yi. Awọn oguna-gbongbo dokita igba na ni egbogi oloro kan ti awọn Oyinbo Jamani (German) lo lati fi ja ogun nigbana ni o fa arun yi.

## Aiye Nlo

Bi amodi luku-luku yi ba ba enia lori irin ni ita gbangba o di ki oluwarẹ fi ọrun kọlẹ ki o ma pọka iku. Ẹnikẹni ti o ba ti fole ti mọ wipe on ti gba ọjọ iku niyẹn a fi ẹniti Ọlọrun ba yọ.

Lẹhin eyi ninu ogun agbaiye keji ti awọn alagbara ṣẹṣẹ ja tan, awọn Oyinbo ologun tun wa ẹtu-ibọn oloro kan ri ti nwọn npe ni atomic bomb. Ibikibi ti nwọn ba gbe fọ ẹtu-ibọn na si di ibi egbe, o di ibi iparun. Gbogbo ara ilu na, ati ẹranko pẹlu ohun ọgbin a parẹ patapata. Awọn ti Ọlọrun ba dasi koni jẹ enia mọ.

## A Nto o

Nwọn a pa lori bi ẹiyẹ igun. Awọn ọkunrin a di akura, nwọn ko ni le ba obinrin lo pọ mọ; awọn obinrin a di agan, nwọn ko ni le loyun mọ. Ibiti atẹgun rẹ ba fẹ lọ (bi iru ibi bayi si Kano) awọn ara ibẹ pade agbako niyẹn.

Nkan buruku ti nwọn ko jọ, ti nwọn fi ṣe ẹtu-ibọn oloro yi awọn alagbara na ni o ye, nitorina ni gbogbo awọn ara aiye ṣe pa ohun pọ ti awọn mbẹ wọn wipe ki nwọn ye dan ẹtu-ibọn oloro na wo nibikibi mọ.

## Yapayapa De !

Ẹyiti o tun pabambari ni egbogi kan ti mo gbọ wipe awọn ara ilu Oyinbo fi akee kọri wipe awọn ko ni lo o fun awọn aboyun mọ; nwọn npe orukọ egbogi na ni THALIDOMIDE. Ọpọlọpọ awọn ọmọtuntun ti iya wọn lo egbogi yi ninu oyun nitori ki nwọn ba le bi pẹlu irọrun ni nwọn bi ibikubi kalẹ.

Mo gbọ wipe ninu oṣu to kọja yi iye awọn abami ọmọ ti nwọn bi ni ilu Oyinbo ti nwọn ko ni apa, ti nwọn ko lẹsẹ jẹ nkan bi ẹdẹgbẹrin (700) enia. Iye iru awọn abami ọmọ bẹ ti nwọn yio tun bi ninu oṣu yi a ko ti mọ. Nwọn ni egbogi buruku yi ni o fa awọn ọmọ ibikubi yi.

Ninu ọsẹ ti o kọja yi ni Oyinbo alarede kan ti o loyun ti dokita rẹ si ti lo egbogi igbẹbi (Thalidomide) yi fun, ti o si ro wipe abami ọmọ ni on a fi oyun na bi, pe ẹjọ si Kotu wipe ki awọn olotu Ijọba ilu

Amẹrika jọwọ ki nwọn jẹ ki on yọ oyun na. O ni on ko kọ rara ki on bi ọmọ merin ti nwọn a da ṣaka saka, sugbọn ọmọ ti ko ni lọwọ, ti ko ni lẹsẹ, ki on kuku su u danu tẹ on lọrun.

Mo gbọ wipe awọn Oyinbo kan ti nwọn nta egbogi ni ilẹ yi ti ko iru egbogi bẹ wọlu sugbọn orukọ miran ni nwọn tẹ si i lara bayi DISTAVAL.

Nitorina emi Olofintoto Eleti Ọfẹ ṣe ikilọ fun ẹnyin obinrin ti ẹ fẹran orisirisi egbogi lati ma lo, ki ẹ sọra nitoripe egbogi ti o nfa arun yapa-yapa ti de ile aiye nisisiyi.

---

## " Omo Erin" Ni

## TANI JEBI ỌRỌ YI ?

Jọwọ maṣai gba mi laye diẹ ninu Iwe Irohin rẹ lati fi ibere ọrọ mi yi si iwaju awọn ọkawe rẹ.

Ẹ jọwọ gbogbo ẹnyin ọkawe Irohin Eleti-Ọfẹ yi ẹ maṣai la ọrọ yi yewa o, Tani o jẹbi ninu awọn mẹfẹfa yi?

Agbẹ kan wa o ni akuko adiẹ kan ti o ntọju, ṣugbọn bi ilẹ ba ti mọ ni o ma nfun akukọ yi ni onjẹ, bi o ba si tun di igbati yio ba sun lalẹ, Agbẹ yi yio tun fun akukọ yi ni onjẹ ki o to sun.

Ni ọjọ kan ara Agbẹ yi ko da, bi ere bi ere amodi yi nwọ Agbẹ yi lara. Ki a ma wulẹ fa ọrọ yi lọ titi mọ, Agbẹ yi sare lọ si ọdọ Babalawo wipe ki o ba on yẹ amodi on yi wo nitori on ko mọ bi amodi on ti nlọ yi.

Bi Babalawo yi ti ri iduro Agbẹ yi, o sare gbe ọpọn ifa rẹ; bi o ti gbe ọpẹlẹ rẹ sanlẹ ni oba ki ifa na fun Agbẹ yi wipe ki o f'ọwọ b'alẹ, ki o fi kan aiya, ki ọ si taka lemẹta wipe ki iku rekọja lori on.

Babalawo na tun wa sọ fun agbẹ yi wipe o ni akukọ adiẹ kan, bi o ba ti de ile bẹni ki o mu akukọ rẹ na ki o tete yara paa, ki o fi ru ẹbọ, ki iku ba a le re kọja lori rẹ.

Agbẹ yi dupẹ pupọ lọwọ babalawo yi. O si mura, o gba ile rẹ na lọ.

Bi agbẹ yi ti de ile ni o ba gbe agbado, o wa bẹrẹ si pe adiẹ rẹ akukọ yi wipe "Kuku, kuku, kuku, kuku." ki o le tun wa jẹ agbado.

Akukọ adiẹ yi bẹrẹ si wo olowo rẹ wipe kini ṣe olowo on loni, tabi ko mọ wipe on ti jẹun ni, adiẹ yi nwo olowo rẹ, ko sunmọọ, bi o ti nsọ agbado si i ni ọkọkan bẹni adiẹ yi nfi enu gbe e ti o tun nsọ ọ silẹ, nigbati olowo rẹ ri wipe ko jẹ agbado ni o ba sare mọ ọ wipe ki o mu u, ni adiẹ yi ba nsalọ ni o ba gba lẹ e ti o nlẹ e lọ rẹrẹ rẹrẹ; bi o ti n'e adiẹ lọ, bi o ti fẹ mu u, igi Iroko kan wa ni itosi ile rẹ, bẹni adiẹ yi ba fo si ori igi iroko na bi o ti fo si ori iroko yi tan ni agbẹ yi ba nwo oke wipe boya on le ri ọna ti on yio fi le adiẹ yi kuro lori iroko yi.

Nigbati ọrọ ti da bayi kini ẹ ro pe igi iroko yi wa ṣe? O sọ lọkan ro bayi wipe on ko le gba'bọdi, nitori iroko ti o ba gba'bọdi, o nwa ija sango bẹni on ko si fẹ ija sango lati ri rara. Iroko yi ko se'ni ko seji, nṣe ni o ba ya ẹka ti adiẹ yi duro le lori silẹ.

Ṣamọṣamọ, a si sọ malu kan wa ni abẹ igi iroko yi, bi o ti gbọ gbura ti igi na ya, ni malu ba bẹrẹsi sare pe ki igi na ma ya pa on. Bi o ti nsare lọ, iya kan ti o n ṣatẹ awọn igba silẹ ni malu yi ba rọ lu awọn igba rẹ gbogbo igba na ba fọ.

Ọrọ wa di janto, iya bẹrẹsi ki gbe malu, ni awọn mejeji ba fi ija pẹẹta.

Abọ mi ni yi o, ẹnyin ọkawe wa, tani o wa jẹbi ninu awọn mẹfẹfa yi?

Ọrọ mi tun di igba miran.

---

**Ewo oju ewe karun fun Irohin Ayiluka**

---

ELETI-OFE

ANJUWON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos. CABLES & TELEGRAM "ELETI OFE," LAGOS

P. O. Box 468 Phone 23370.

VOL XIV. No. 832 SATURDAY AUGUST 11,-AUGUST 17, 1962

# Kini O Fa Eleyi ?

Awon agbalagba ni ilu Hausa ni nwon ma npa owe kan wipe oba mewa igba mewa. Nitoto ni ojojumo ni aiye nyi. Aiye Alafin Abiodun o yato pupo si ti Oba Alafin Ladigbolu. Bena si ni aiye Oba Alake Gbadebo omo Efunnmi yato si ti Baba wa, Oba Ladapo Ademola.

Nkan ti o fa oro arofo awa Eleti-Ofe ti ose yi ni nipa opolopo iwe ati ibere ti a ti nri gba nipa oro a-nkania a ko kania ati pe iye bayi bayi ni awon omo enia ti o wa ninu ipinle kan.

Otito oro bi isokuso ni o ma nri; sugbon awa oniwe irohin Eleti-Ofe a ko ni kuna lati ma fi otito han enyin ti o nka'we wa nitoripe otito ni a fi bere iwe irohin wa yi lati iwon nkan bi odun mokandinlogoji sehin

Oro otito ti a gbo nipa oro a-ka-ni a-ko-ka-ni yi fe mu ariyan jiyan wa lodo awon ara Ipinle kan ti nwon nfe ki awon akowe aka'nia so wipe awon ni o po ju, ati pe nitori oro ariyan jiyan yi ni ko ti je ki nwon gbe iwe gbogbo enia ti won ti ka na jade.

Gbara ti nwon ti gbo wipe otito iye enia ti nwon ka jake-jado yi ti jade ati wipe nkan ko ri bi awon ti pee mo, opolopo iwe beko, beko ni nwon ti te jade fun araiye gbo nitoripe iran ti nwon ni nwon fe ki o ma se olori Ijoba Apapose.

Kilo fa ? Akuko adie ni o fi o gbe orire fun kolokolo yewo, iyen ni ti enyin Yoruba ti e to aso wo ti e nso aso ko.

Oro re o !

---

OLOFINTOTO ELETI—OFE ni Arun YAPAYAPA ti de ile ayie. ...... Ka oro re ni oju ewe keta pelu oro OMO ERIN. E ti gbo oro Omo Erin yi ti pe.

---

# Iwe Si Olotu

## A Ki Gbele Gbo'fa Nitoto

OLOTU, mo gba fun oro lakaye ti e so fun wa ninu iwe nyin ni aipe yi ti e se ikilo fun awon ti o ma nlo pe si ori kereni pajawiri ti nwonse si Idumota l'Eko bi eniapataki kan ba mbo wa si ilu Eko lati ilu okere.

Eru ba mi pupo nigbati mo ri ogunlogo awon enia ti nwon lo gegun s'ori Kereni pajawiri na lojo ti Oloye Obafemi Awolowo fe wo'lu Eko.

Gbogbo awa ti a fe gba ona ibe lati lo se ise pataki a ko ri ona lati gba lojo na.

Kereni ohun, ewu ija-mba ti wa nibe ti o poju, nitoripe kereni yi ko ni agbara rara, o si le wolule bi enia ba po pupo lori re.

A dupe lowo nyin fun ikilo ti e se fun awon ara Eko ki nwon ye fi emi won wewu.

Emi ni,
Apapa A. Williams

---

## Eko Akete Ile Ogbon Da ?

O to ose keta nisisiyi ti a ti ri iwe itan Ogbeni Onatade ti o nko nipa ilu Eko ti o npe ni Eko Akete Ile Ogbon ka - se ko si nkankan l a r a ara kuurin wa na ti a ko fi ri itan na ka mo tabi o ti tan ni ?

E jowo, e ba wa gba Ogbeni Onatade na ni imoran ki o jowo ki o tun ba wa so itan na si iwaju si nitoripe a ngbadun re.

Emi Ola yio gun o, iwaju ni opa ebiti a mo resi.

Emi ni,
Agbeni Modupe
Ibadan

---

## ANNOUNCEMENT

THE NIGERIAN PORTS AUTHORITY has pleasure in announcing that arrangements has been concluded for a NORTHERN REPRESENTATIVE (MALLAM ABDULLAHI OBADAKI) to be permanently domiciled in KANO in an office to be shortly opened in the new building of the Northern Region Marketing Board, Post Office Road, Kano.

A further announcement will be made as soon as a definite opening date has been fixed.

NPA Notice No. 733
25th July, 1962

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

## Iye Di Pupo

Ọladipupọ ni nwọn ma ngbọ ninu ile wa ni aiye atijọ ṣugbọn nisisiyi aiye ti di owo-di-pupọ, ile-di-pupọ, ọmọ-di-pupọ, iyawo-di-pupọ, gbese-di-pupọ, ọlọgbọn-di-pupọ, ati pe ni ilu Onitsha nisisiyi ọrọ Obi-di-pupọ, iyẹ-di-pupọ, orișa-di-pupọ.

Mo gbọ wipe awọn eniyan pataki pataki ni o ndu ipo oye Obi ni ilu Onitsha nisisiyi. Nkan ti olukuluku a ṣe fun wa ti nwọn ba de ipo na nwọn ko ti sọ fun wa, bi nwọn a sọ wa dẹru ni, bi ọmọ atata ni nwọn a sọ wa da ni, a ko ti mọ.

## Ona Ofun

Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba de ibẹ ninu awọn Ọbalọla yi ki o ti obi-abata pupọ r a n ș ẹ si mi ki nle ri nkan fi bọ orișa-kekere-a-kunlẹ-bọti o wa leti Odo Ọya nitoripe ọna ọfun ni ọna ọrun.

Ẹ tilẹ duro na emi alara paapa ni ẹtọ si oye Obi yi. Awọn ara Onitsha ni ọmọ Oduduwa ni awọn, nwọn ni Ibini ni awọn ti wa do si ilu ti nwọn npe ni Onitsha loni, nwọn ni nitori ọtẹ kekere kan ni awọn ṣe sọda Odo Ọya si ilu yi. Ọrọ wa diọrọ ẹniti o ba fẹ jogun gbọingbọin ti a tilẹkun gbọingbọin.

Orukọ temi Ayiluka ni ti Onitsha-Ibo ni OSITADẸMA. Ọrọ pọ ninu orukọ mi na, ṣugbọn ẹniti o ba gbọ ede Ibo ti ara ile, ti kiṣe ti awọn ara oko, a mọ nkan ti OSITADẸMỌ jẹ.

Kọmi si a nu! Ibo ni mo fọ yẹn o. Mo ni daradara ni ao tun pade. Iyẹn bẹ.

## Odo Ogun

Mo gbọ wipe ni ilu Abẹokuta, awọn ọmọ Lisabi ti tun și omi-ẹrọ tuntun. Emi Ayiluka ki gbogbo ẹnyin ọmọ Olumọ Abẹluku wipe ẹ ku orire. Lẹhin ilu Eko ti awọn Ijọba Oyinbo kọ pese omi-ẹrọ fun, awọn ọmọ Ẹgba ni o tun tẹle ilu Eko lati pese omi-ẹrọ fun ilu wọn niwọn nkan bi ọdun mejidinladọta sẹhin laiye Ọba Gbadebọ, ọmọ Efunwunmi. Ọrun re o.

Mo gbọ wipe nisisiyi a le fa omi odo Ogun bi o ti wu wa, a le mu awọn Oyinbo onișẹ onișowo wọlu, nitoripe omi wa ni jaburata lati fi ṣe iṣẹ ti nwọn ba fẹ da silẹ nilu Ẹgba: mo gbọ wipe mo le mu awọn Ọmọ-jaiye-jaiye wa ṣe'gba nilu Ẹgba nitoripe omi wa ti nwọn le fi wẹ ti a ba jaiye daradara ni Agọ Owu tan ti a gba Itoku lọ, ti a wa pari gbogbo rẹ si ọja Ibarapa l'Ake.

Ni ẹmii (ọdun ti mbọ) ma mu awọn ẹlẹyinju-ẹgẹ obinrin wa bọ Iyemaja (odo Ogun) ma tun bọ Odo Lafunyẹnrẹn ni Agọ Owu, ma tun wa lọ bọ odo Gbangba ni Agọ Ijaiye.

Iyemaja, mo juba rẹ o, ki o ma ṣe fi jamba ṣe wa nilu Ẹgba tọmọ tọmọ.

## Yawo-yawo

Irohin kan ni o sẹṣẹ kan mi ni ijẹta ọjọ re; mo gbọ wipe awọn oguana gbongbo oṣelu kan ṣẹṣẹ da ẹgbẹ kan silẹ nilẹ yi ti nwọn npe ni "EKE LOJU O-TI". Iṣẹ owo yiya ni nwọn nṣe. Mo gbọ wipe Ọgbẹni (tabi Dokita ni ki a pe e?) Adekoye Majẹkodunmi paapa ti kọwe si wọn lati ya nwọn fi san owo oṣu awọn akọda Ibadan, owo-oṣu awọn wole-wole Ogbomọshọ, owo-oṣu awọn Adajọ Ọyọ ati owo-onjẹ awọn ẹlẹwọn ni Agodi. Ọrọ owo-oṣu ti awọn akọwe Oritamẹrin ko ṣoro, gbogbo awọn ti o ba gba mọto-ayọkẹlẹ ni san-diẹ-diẹ ni nwọn a wa batiṣe. Ọtẹlẹmuyẹn Ayiluka ni on gbọ wipe nwọn ti kọ iwe kan si awọn baba onimọto na pe okun le pupọ nisisiyi, Aganyin ko gbọdọ wẹ.

## Esu Adaako

Ọrọ owo yiya yi mu mi ranti arakunrin wa kan, Ogun Shofọlahan ti o ku ninu ọsẹ yi ti awọn ara Eko nma npe orukọ rẹ ni "OF IGBORE" ọmọ Abẹokuta. Iṣẹ akanbata ni arakunrin wa na ti nma nṣe ni Oke Arin l'Eko ri ki o to bẹrẹsi ṣe iṣẹ owo-ele, o si gbajumọ larin awọn obinrin Eko O yẹ ki awọn oṣiṣẹ Loko l'Ebute-Mẹtta ṣe aṣeyẹ ni ibi ijọ mẹjọ oku rẹ nitoripe arakunrin na sin wọn jọjọ pẹlu esu-adaako, ọmọ ti o bi pọ pupọ boya awọn na le ri fẹ ninu wọn.

Ẹ ba mi ki ọrẹ mi Ayinde Ọjọyẹ ti G. B. Ollivant, o ku asẹhinde; ọjọ yio jinna sira wọn.

Ayiluka a sọ diẹ nipa Ibadan l'ẹmọ ẹ ko mọ layipo ninu ọsẹ ti mbọ fun yin.

# Dokita Yi Nwa Ogbon Si



Dokita David S. Dane ẹniti o wa ninu aworan yi nwa ọgbọn siwaju si lati ma wo aisan san lai gun enia ni abẹrẹ. Dokita yi ni awọn tiẹ akiyesi wipe ọpọlọpọ enia ni nwọn ko fẹ ki wọn lo abẹrẹ fun awọn ti nwọn ba wa ninu aisan.

## Ikomo Arikewuyo Dun

Ẹnu kọ irohin ni ikomọ 'kunrin ti Ọlọrun fi ta Alhaji Busari Yaayi Arikewuyọ ati aya rẹ, Suwebatu Ọmọyaayi Arikewuyọ lọrẹ. Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni nwọn ṣe ikomọ na ni agbo-ile wọn, 2, Ewena Court.

Imam Deen Bello ti Mọsalaṣi Ọlọrọ ni o ṣe eto isọmọ na loruko, Alhaji Lawal Da Imam Shaki si tan an lọwọ, nwọn si sọ ọmọ na ni Abudulai Ọlanrewaju Arikewuyọ. Ẹsẹ awọn Alhaji, imam, alufa ati gbajumọ ni o pe ṣọṣọ si ibi aseyẹ isọmọlorukọ na, nwọn le ni igba (200) enia.

Baba ọmọ na ati Alhaji Awaiyewaṣere, ọrẹ baba ọmọ na si na wabi-wọsi o w o. Ajẹti ati amuti ni awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na fi onjẹ adidun ati tii oniwara oyinbo ṣe lọjọ na.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni Alhaji Y. A. Disu (Awaiyewaṣere), Alhaji Mhd. Lawal (Ibadan), Alhaji Abudu Whab Shittu, Alhaji Olowo (Iseyin), Alufa Bakre (Ẹdẹ), Alfa Fasasi (Kishi), Alfa Salawu (Iseyin), Alfa Yesufu Amuda (Iseyin), Alfa Amidu ati Ọgbẹni Yunusa Taiwo Adeoye.

Ki Oluwa ṣe ọmọ na ni olori ire, ki o si fi ire kari o.

# Ise De Fun Awon Alufa Akewu

IBADAN—A gbọ irohin wipe awọn Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun fẹ gba awọn Alufa Akewu sinu iṣẹ tiṣa lati mọ kọ awọn ọmọ ni kewu (Arabic) ninu ile iwe Ipinlẹ Iwọ Orun na jake jado. Gbobo awọn ti nwọn yio gba si ibi iṣẹ na, ko ba ṣe ọkunrin tabi obinrin ni, nwọn ni lati ṣe idanwo pataki kan ni ede Gẹsi ati ni Yoruba ninu oṣu ti mbọ.

A tun gbọ wipe lẹhinti nwọn ba ti ṣe idawo yi tan ni ilu Ibadan, Akurẹ Benin, Ijẹbu-Ode ati Ọyọ, nwọn a tun ṣe eto pataki fun awọn ti o wa ni agbegbe Sapẹlẹ ati Eko lati ṣe idanwo ti wọn ni Warri ati Ikeja.

Awọn ti o ba yege ninu idanwo wọn, owo ti o ṣe gbukẹ ni nwọn yio fi bẹrẹ fun wọn.

## Awon Olosa Da Onisowo Kan Lona

IJẸBU-ODE — Ni ẹnu lọlọyi ni awọn ọlọṣa danadana kan da obinrin oniṣowo kan ti orukọ rẹ njẹ Nikẹ Barikisu, ẹni ogoji ọdun lọna, nwọn si gba adọta-lenirinwo pọnun (£450) ti o nmu lọ ra ọja lọwọ rẹ larin ọna Ijẹbu-Ode si Eko.

Ni ọjọ ti nkan yi ṣẹlẹ, Barikisu ni on ati dẹrẹba mọto on ni awọn nlọ si Eko lati lọ ra awọn nkan ti on nta; o ni bi awọn ti rin de ibusọ mejidinlogun ni awọn pade awọn ọlọsa yi ti nwọn da mọto awọn duro. Nwọn ni ki o fi owo ra ẹmi rẹ. Obinrin yi ni ni on ba ko gbogbo owo ọwọ on ati ẹru inu mọto fun wọn.

Bi awọn ọlọsa yi ti gburo mọto miran ti mbọ ni nwọn ba fẹsẹ fẹ ẹ. Ọwọ ọlọpa tẹ ọdunrun pọnun (£300) ninu owo ti awọn gbe na nigbati nwọn bẹrẹsi wa wọn kiri ninu igbo.

## Ayiluka Ni

## Ibadan Ni O Mo, O Ko Mo Laipo

## Ka iwe Eleti-Ofe lose ti mbo.


Advt. No 134

### NOTICE

NIGERIAN HONOURS, DECORATIONS AND AWARDS

The National Committee on the award of Nigerian Honours would welcome suggestions from the general public on the following questions:-

(i) Do you consider that there should be only one set of National Awards, or do you consider that there should ALSO be Regional Awards either for services rendered to the Regions or in recognition of visiting foreign dignitaries ?

(ii) Do you consider that such awards should take form of:-

(a) titles, which qualify recipients to use letters after their names, or
(b) decorations, which qualify recipients to wear medals on ceremonial occasions, or
(c) both, or
(d) neither ?

(iii) Do you consider that Foreign Honours should be accepted by Nigerians, with or without the approval of the Federal Government ?

2. Please address all communications to :-
The Secretary,
National Committee on Nigerian Honours,
c/o Cabinet Office,
LAGOS.

3. It will be appreciated if your suggestions are forwarded to the Secretary not later than the 30th of September, 1962.



## OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ENITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA. BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN, EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE

TI ỌJA LE FI MA TA
BI IṢU AKARA GBIGBONA.
POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—ỌFẸ



## ELETI--OFE

DARABA

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe.

# Freedom From Hunger

## (By A Special Correspondent)

HUNGER is man's oldest enemy. Today, in the midst of vast technological and scientific development, this ancient struggle continues and becomes more acute.

Of the word's 2,800 million people, about one-half of them are seriously under--nourished. Not more than one in a hundred of all these people will ever be likely to have what is normally considered to be a good square meal. Their diets are not only low in calories but are unbalanced, consisting mainly of cereals and starchy foods.

### Sickness

Protein malnutrition, anaemia, goiter and rickets are some of the more common deficiency diseases in most under-developed regions, all of which are taking a serious toll in premature death, physical and mental vigour, human activity, imagination and knowledge.

These grim facts were presented to employees of Massey—Ferguson this month in their world-wide company magazine "M-F VIEW." The article continues by pointing out that the problem would be big enough if this were all, but there is a further complicating factor.

### World

Every day there are 140, 000 more people in the world. If present trends continue, almost 4 billion people will be in the world by 1975 and about 6 billion by A.D. 2000. What plans are being made to meet the food and nutritional needs of this future population growth?

### Farmer

In very simple terms, states Massey—Ferguson, the answer to the world food problem is to bring to the underdeveloped countries the techniques which have brought material prosperity and freedom from want to the highly developed areas.

For the most part, the backward farmer does not lack land so much as the knowledge, skill and resources to make the most of the land he has. Ample proof of the prospects here is found in countries where crop areas have been reduced in recent years while food production countinues to mount.

## Speaker's Chair For Nigeria

LONDON— Before it is despatched to Nigeria the Speaker's chair for the House of Repesentatives which Britain's House of Commons decided to present to mark Nigeria's independence will be on display in the library at Westminster for Members of Parliament and their guests to see.

It will actually be handed over to the Nigerian House in November by a delegation of about five British Members of Parliament whose names will be announced within a few days.

It is expected that some if not all of the delegation members will be going to Lagos in November as Britain's representatives to the Commonwealth Parliamentary Association Conference.

This annual conference is being held in Nigeria for the first time. About one hundred and twenty members from all Commonwealth countries usually attend. This year's Association Chairman is Mr. R. A. Njoku, Nigerian Minister for Transport and Aviation.


## NIGERIAN PORTS AUTHORITY

VACANCY – ELECTRICAL ENGINEERING SCHOLARSHIPS

The Authority proposes to award a number of scholarships to suitably qualified Nigerians who are actively pursuing courses of education which will lead to qualification as Electrical Engineers.

QULIFICATION.

Candidates must have passed one of the following examinations at a high level :-

(a) Intermediate B.SC. (Eng).
(b) Ordinary National Certificate (in electrical subjects).
(c) G. C. E. (Advanced) in Mathemathics and Physics.
(d) Higher School Certificate in Mathematics and Physics.

The successful candidates will be sent to the United Kingdom to complete their course of study, either to B.Sc. or Higher National Certificate, and will be expected to take any additional subjects to qualfy themselves academically for Associate Membership of the Institution of Electrical Engineers. The Authority will also provide them with sufficient opportunity to obtain the requisite Practical experience.

The successful candidates will be provided with passages to and from the United Kingdom by air, tuition fees and a salary in accordance with the Authority's scales. In return they will be expected to enter into a bond with the Authority by which they will be bond to serve the Authority for a minimum of five years after qualification.

METHOD OF APPLICATION.

All applications should give full details of age, qualifications and experience, and forwarded to reach the Personnel Manager, Nigerian Ports Authority, P.M.B. 12588, Lagos, not later than 31st August, 1962. Applicants in Government Departments and Statutory Corporations should forward their applications through their Heads of Departments who are requested to attach Confidential Reports before submitting them.

N.P.A. Notice No. 751.
6th August, 1962

BAYO KEHINDE
Secretary to the Authority.

## Tani Ge Owo Koko?

# Adeyi Ni Awon Agbe Alara Ni

ĘKO—Ninu ọsẹ yi, ni iwaju awọn igbimọ oludari iwadi (Ęnkuari) ti nwọn nwadi ọrọ ajọda-iṣẹ mẹfa ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye A. O. Adeyi, ẹniti o ti nṣe Minisita alabojuto iṣẹ ọwọ ati owo Ipinlẹ na ri ni o fi gbogbo ọsẹ yi jẹri niwaju awọn oludari iwadi na.

Oloye Adeyi, ara Fiditi lẹba Ọyọ ni iṣẹ tiṣa (teacher) ni on ti nfi igbakan ṣe ki awọn Ęgbẹ Afẹnifẹre (AG) ti ilu on to yan on si ile igbimọ ti awọn ogunna gbongbo ẹgbẹ na to gbe iṣẹ minisita alamojuto iṣẹ ọwọ ati iṣẹ owo le on lọwọ, on ko fi igba kan kọ iṣẹ owo (economics)

Oloye Adeyi ni on niran osu January ọdun ti o kọja (1961) nwọn ni ki on pe apejọ gbogbo awọn agbẹ si Ibadan; On si pe e, awọn ti o wa si ibi apejọ na lojọ na lohun ni Oloye S. L. Akintọla, tiṣe Olotu Ijọba Ipinlẹ na nigbana pẹlu diẹ ninu awọn Minisita rẹ. Lẹhinti awọn ti ṣe alaye bi ọrọ koko ti nlọ ni gbogbo agbaiye si, awọn kuro ninu ipade na, awọn si fi awọn agbẹ yi sile ki awọn le JIRORO nkan ti nwọn fẹ ki awọn ṣe nipa ọrọ koko (cocoa) yi.

Nigbati awọn tun pada sinu ile ipade na, awọn agbẹ na si dupẹ lọwọ awọn gidigidi fun wahala awọn gẹgẹbi Ijọba lori ọja Koko, awọn si ti ṣe ipinnu (resolution) wipe ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ge owo koko ku ki inira ma ba ba Ijọba lori owo sisan.

### ĘSUN LORI AKINTỌLA

Ni ọsan ọjọ Aiku, ki nwọn to tuka nibi iwadi na, Ọgbẹni G. B. A. Coker, alaga awọn oluwadi ni on fun Oloye Awolọwọ ni wakati mẹrinlelogun lati fi mu iwe ẹsin mẹrinlelogun ijọ kinni ti awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) fi Oloye Akintọla sun ti nwọn ni o jẹbi, wa si iwaju on.

Sugbọn ni ana, Oloye Awolọwọ ni nkan mẹta pataki ni ẹsun ti awọn fi Akintọla sun ti awọn si ṣe idajọ le e lori, lori awọn ẹsun na.

## Omi Ba Oju Ona Moto Ajase Je

IDIROKO—Gbogbo awọn onisowo ara Ajasẹ ti nwọn wa si Eko lati ilu bi Kutọnu ati Lomẹ lati wa ra ọja tita ni ẹkun omi semọ nigbati nwọn npada bọ wa sile ninu ọsẹ yi. Omi kun oju ọna mọto ti awọn mọto akero na ni lati gba pẹrẹwu. Opọlọpọ awọn onisowo yi ni nwọn fi ori ru ẹru wọn lati inu mọto, ti nwọn si nwọ odo tulasi yi kọja si odi keji. Awọn ti o ngbe itosi ibiti omi ya si yi gbe ọkọ oju-omi kekere wa sibẹ lati ma fi ko awọn enia sọda pẹlu ẹru ti ko ba wuwo pupọ ju.

### Dahomey Di Ore Nigeria

Ninu ekun omi yi ni awọn asoju Ijọba ilẹ Nigeria ati diẹ ninu awọn asoju Ijọba ilẹ Dahomey (ilu Ajasẹ) wa si ọcu ala awọn Ijọba mejeji ni jarun ọjọ Isẹgun tiṣe ọjọ kejọ oṣu yi lati wa si ẹrọ isọrọ-si-okere (tele-link) eyiti o sọ awọn ara ilu Ajasẹ pẹlu ara Nigeria di aladugbo, eyi a si le jẹ ki ẹnikẹni lati orilẹ ilu mejeji le ma ba ara wọn sọrọ.

Tẹlẹtẹlẹ ko si iru anfani bayi fun awọn ara Ajasẹ nigbati ilu na wa labẹ awọn Oyinbo Faranse. Ni ọsẹ ti o kọja ni ilu Dahomey ṣe iranti ọjọ ti awọn gba ominira (ọdun keji) lọwọ awọn Oyinbo Faranse yi.

Gẹrẹ ti nwọn ti ṣi ẹrọ isọrọ-si-okere yi tan ni Gomina-agba Ijọba ilẹ Nigeria, Ọlọla Dokita Azikiwe ti gbe ẹrọ yi ninu ile Ọba ti o ngbe ti o si ki Alakoso Ijọba ilu Dahomey, Hubert Maga, pe "O ku o nibe yen, e si ku orire ti gbogbo eleyi se oju wa!"

Lẹhin eyi Ọlọla Alhaji Tafawa Balewa, Olotu Ijọba Apapọ ile Nigeria tun ba Ọgbẹni Maga sọrọ lori ẹrọ idera yi.

# Keke Iroko Fun Obinrin



**O binrin Oyinbo ti o wa ninu aworan oke yi nfi keke afuye kan ti nwon se fun awon obinrin lati ma fi ro oko ninu ogba won. Obinrin yi ni ko si nkankan ti a won okunrin nse ti awon na ko le se. Awon okunrin mbo sokto awon na mboo, nwon tun nroko awon na tun mb wod roko.**

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; EDITOR (OLOTU): OLA. ONATADE
15 Kosoko St., Lagos,